# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

VOL. I. NO. 16. SATURDAY, OCTOBER 28, 1922. THREEPENCE.

*Editor:*—ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### ẸWỌN LO NRO ṢAFC (A-WA ỌKỌ *MOTOR* KAN).

A kilọ gidigidi fun enia-lasan kan ti o nwa *Motor L104*, pe irufẹ iwa t' o hu ni ọsẹ to kọja ti o mọ-mọ tẹrẹ fi *Motor* na re awọn Ọgbẹni D. O. THOMAS t' o nṣiṣẹ ni Ibode (*Customs Agent*) ati ADELANI GBOGBOADE Onişẹ-Ọba ni Ibode (*A Clerk in His Majesty's Customs*) s' omi lori afara DENTON nigbati nwọn nbọ wa ile lati ibi oku, Ọgbẹni RHODES l' Ebute-Mẹta, le gbe e ju s' Ẹwọn ti ko ba kiye-sara; nitori a gbọ pe nigbati awọn bọkinni yi jaja bọ ninu ewu yi, lati ori *Bicycle* wọn, ti Ọgbẹni THOMAS si pe e lohun-rara pe ki o duro wo jamba t' o fẹ ṣe wọn, ẹrin ni alakọsi na busi gbã-gbã. A ki awọn enia yi "ku-ewu." A fẹ ki awọn Ọlọpa kiyesi a-wa *Motor* yi *L104* daradara.

### PAGIDARI!

Anu ṣe ni lati gbọ pe Ọgbẹni S. A. FATOLU, Akọwe Oyinbo D.O. ni Ijẹbu-Ode ti a ba ro 'jọ pe o ja 'ba nipa gbigbe enia kan ti-mọ-le ni adabọwọ-ara-rẹ ni Ijẹbu-Ode, jẹbi ẹjọ na ni KOTU (*Assize*) ti a ṣe ni Ibadan ni ọsẹ to lọ: Adajọ SIR F. A. VANDER MỤLEN l' o da 'jọ na: a si sọpe ki Ọgbẹni na san ọgbọn pọun' bibẹkọ, ko lọ si ẹwọn oṣu mẹfa: Ọgbẹni yi san owo na, ṣugbọn o tun gbe ẹjọ dide si GANRAN l' Eko nibi. Ọgbẹni MONTACUTE THOMPSON l' o ba ṣe ẹjọ yi ni Ibadan.

KABỌ, BALOGUN MEYAKI.

A ki Ọgagun H. C. MOORHOUSE Oloye C.M.G. "Kabọ" lati ilu rẹ, lẹhin isimi oṣu mẹfa ti o ti gba lọ si 'le. Ọgagun na ba Ọkọ-Elefi "*Ekari*" de ni *Saturday* to kọja. Alafia ki 'le wa bi?

ARA ILU, Ẹ KU EWU, EWU INA KI I P' AWODI, AWODI, Ẹ KU EWU.

Ni arọ *Friday* ọsẹ to kọja, ewu nlanla kan wu awọn enia t' o nlọ t' o mbọ lati ọna Ebute-Mẹta: bi *Motor* Alaru gbangba ti awọn Oyinbo GRACE BROS. ti fẹ ya fun *Motor* Jẹ-lẹ-nkẹ ti ARAOTI (MRS C JOHNSON) bẹni *Motor* gbangba yi si fori sọ awọn opo irin tẹrẹ-tẹrẹ to wa 'leti afara na (CARTER BRIDGE) ọgafa, o-di-wọ ninu omi! a gbọ pe obinrin Hausa kan t' o nfi ẹsẹ rin lọ niti ara rẹ fi ara pa diẹ.

A dupẹ pe ko si ẹmi ti o ṣofo lọna bayi.

"EṢU ṢE E, KO DURO DE MI."

Irufẹ orin yi ni a le sọ pe ọkunrin aṣiwere kan nkọ ni Alamisi (*Thursday*) ọsẹ ti o kọja ni ọjọ *19* oṣu yi, nigbati aṣiwere na yọ ãke ti o si sa si oke-aja Ile-pẹtẹsi awọn Oyinbo MACIVER ni Apapa, ti o nda gbogbo enia t' o ba fẹ sun mọ ọ lãmu; o ṣa oyinbo kan lapa, ati SAJI (*Sergeant*) ọlọpa kan ni iwaju, o ni ki awọn enia to wa nibẹ fun on l' onjẹ ki on ba le sọkalẹ, nwọn fun u, ṣugbọn sibẹsibẹ ko sọkalẹ; awọn Panapana l' a ranṣẹ si, ti nwọn wa ki i lọrun mọ 'lẹ nikẹhin. A gbọ pe ọkunrin yi jẹ ọkan ninu awọn "Lebira" awọn Oyinbo ARMSTRONG Onişẹ ni Apapa, ati pe ko si ohun to se e ṣãju ọjọ yi, lojiji ni were na "lẹ'di si i."

ILE-ẸJỌ ẸRU-JẸJẸ

Ile-Ẹjọ awọn *Jury* yio ṣi ni *Monday* ijọ kẹfa oṣu *November* ti o nbọ. Adele Adajọ Agba (ABERIN-ṢEFUJA, Ọlọla A. R. PENNINGTON, K.C.) pẹlu awọn "Abẹyọ" rẹ, yio kọkọ lọ ṣe Isin ni Ṣọọṣi Alagogo (*Christ Church*) gẹgẹ bi iṣe wọn lakoko yi l' ọdọdun,, ki o to wa bẹrẹ Iṣẹ. A ti nfi iwe pe awọn SARAKI ni ilu lati wa sin 'ba diẹ' ninu iṣẹ *Jury*.

A RI IYAWO KỌ 'YALE?

A ṣakiyesi pe nnu awọn enia ti o lọ si Ariya Alake, ADEMOLA KEJI, nigbati o nṣe Ajọyọ Adọta ọdun ti a ti bi i, a ko ri awọn enia wọnyi lãrin wọn. Awọn Bọkinni ADEBESIN FOLARIN, Lọya, Dr AKIWANDE SAVAGE, ati pãpã Ọgbẹni J. K. COKER, laisi ani-ani, awọn enia mẹtẹta wọnyi ṣe gudugudu-meje fun LADAPO ADEMOLA ỌMO-ALADE ki o to di ẹnití gbogbo Ẹgba fẹ ki o gun Ọri Itẹ ni ọdun Ekeji ọhun. Kã si nkan?

PASTOR IṢỌLA ṢE 'HUN ÀRÀ

A ba Ojiṣẹ-Ọlọrun, PASTOR A. ADEDEJI ISOLA Alabojuto, Ijọ *Brotherhood* yọ fun Iwe-Oye (*Certificate of Proficiency*) ti o ri gba lati Ilu-Oyinbo nipa "ti Ijafafa ti o ni ninu Ẹkọ ohun ti Ẹmi" (*Pychological Studies*) Iwe na ba ọkọ "*Ekari*" de ni ọsẹ ti o kọja.

AJỌDUN KẸJỌ TI IJỌ "EBENEZER AFRICAN CHURCH," OGUNPA, IBADAN, NIGERIA, 24TH SEPTEMBER, 1922.

ESTABLISHED AUGUST 1914.

IROHIN KUKURU.

Ni ago mẹta ọsan ọjọ na, ni Ẹni-ọwọ E. A. Obigbẹsan bẹrẹ nipa kikọrin No. 115 lẹhin eyi ni Ẹni-ọwọ ka diẹ ninu Bibeli, Ẹni-ọwọ S. A. Allen wa gbadura.

Akọwe ijọ yi, Ọgbẹni J. Ade. Ọtẹgbọla wa lẹhin eyi o wa pe Ọgbẹni pataki ọkan ninu onisowo nla ni sọrọ kukuru Ibadan J. Ally Johnson ko wa ṣe alakoso ọjọ na, nipa gbigba Aga awọn isọngbe rẹ ni wọnyi:— A. Pearse, Ẹni-ọwọ S. A. Allen, E. O.

Otudeko, M. D. Ogunbayọde, E. Victor Watson, N. S Oke, C. J. Meffle, T. H. Scott, Charles C. L. Ọdẹbiyi, H. O. Williams, O. J. E. Okuyiga, Suberu, T. H. Johnson.

Awọn ti ko le wa :—M. D. Ogunbayọde, C. J. Meffle ati T. H. Johnson.

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Alakoso, J. Ally Johnson wa bẹrẹ nipa sisọ ohun to mu wa wa bi, ọrọ rẹ to sọ o pọ to iwọn abọwakati, nipa didupẹ lọwọ awọn ẹni Ọlorun bi awọn Ọgbẹni, Wicliffe, Akiogun, Ọtẹgbọla, T. H Scott to da ijọ yi silẹ ni ile Isaac Williams ki Oluwa ko ran ijọ yi lọwọ, ki awọn ọmọ ti ati bi ki wọn le ma fi ọwọ sọ aiya wọn, wipe Ile-Isin ọmọ ibilẹ ni eyi. Ede Oyinbo lo sọ o.

Awọn to sọrọ ni Ipade yi ni wọnyi:—N. S Oke, S. A. Allen, C. L. Ọdẹbiyi, E. Victor Watson, O. J E. Okuyiga, H. O Williams.

Awọn to wu ni lori nipa kikọ akanṣe orin ti ati tẹ orukọ wọn si inu iwe eto Isin yi:—Ogbẹni C. L. Ọdẹbiyi ẹniti o kọrin nigba mẹta ni ede Oyinbo ati Yoruba, ẹniti a le sọ wipe nipa ohun duru rẹ ọkan lo jẹ ni Ibadan ọpọlọpọ enia le mọ Ọgbẹni yi ni ile Ẹni-ọwọ J. R. Williams ti ijọ *Baptist* l' Eko nipa ohun rẹ ati awọn Ọgbẹni meji A. E. Smith ati M. N. Sawyerr awọn ẹniti o mu ipade yi dun.

Owo ti a gba ninu ipade yi jẹ iwọn pọun mẹrin o le diẹ.

Alakoso pari ọrọ rẹ nipa gbigba adura ninu ọrọ rẹ wipe Ile-Isin ti a npe ni agọ kan ṣa, yio di (*Cathedral*) Ile Ọlọrun nla lagọ ra Ọlọrun.

Ọgbẹni C T. Dixon wa dupẹ fun Alakoso nipa wiwa ati alakoso to jẹ.

Ọpọlọpọ enia lo wa, gbogbo ile ati ita lo kun fun ero, akọwe ọgbẹni Lọya Shyngle jẹ ọkan ninu awọn alejo to wa.

*Ebenezer* Ọlọrun wa pẹlu Rẹ.

Ipade yi pari ni nkan ago marun abọ ọjọ alẹ.

ALAO.

# OPEN LETTERS. No. 3.

To His Excellency,

SIR HUGH CLIFFORD, G.C.M.G.

Governor and Commander-in-Chief,

of the Colony and Protectorate of Nigeria.

etc. etc. etc.,

GOVERNMENT HOUSE, LAGOS.

Your Excellency,

Never in the annals of Lagos, or of Nigeria, for that matter, was any of our former Governors greeted with so warm, genuine, and royal a welcome as that accorded Your Excellency and your amiable consort on your arrival at our shores on the 8th August, 1919, to assume the reins of the Government of this great Dependency: this spontaneous outburst of popular enthusiasm then manifested, was neither sham nor counterfeit, for it has its inception in the "big" reputation arising from your humane yet Firm system of government with which your great name was usually always associated, whilst you held the Governorship of out sister colony of the Gold Coast, and of which we have heard so much.

Unhappily, no sooner Your Excellency assumed duty in our midst in real earnest, than the ELEKO IMBROGLIO intervened like "a bolt from the blue" and brought in its train, many heart-burnings and grief to this Community as never before.

Much, it is admitted, has been said and written on the regrettable episode, still, I take it, that it is not late for me to appeal to Your Excellency as a Conscientious and Devoted Catholic, whose sense of public duty, I respectfully submit, will not militate against that proverbial FORGIVENESS which, we are told, is the very Bed-rock of AURICULAR CONFESSION forming as it does, one of the Fundamental Teachings of the Church to which Your Excellency has the honour to belong.

It is on this ground alone, I venture to address Your Excellency in the matter, humbly and earnestly praying that your Prerogative of MERCY, as BECOMES A GODLY CATHOLIC, may be extended ONCE MORE to the ill-fated Prince, who, to my thinking, is more sinned against than sinning.

AVE, Your Excellency!!!

EKO AKETE.

## EKO AKETE.

EKO, SATURDAY OCTOBER, 28, 1922.

### IJO-KI-JO MBẸ L' ẸHINGBẸTI.

Ẹsun pataki ti awọn Oyinbo nfi awa Ẹnia Dudu sun nigbakugba ni pe o jẹ aṣa wa lati ma a sin wọn jẹ ninu nkan pupọ lalai ni lakaye ati da nkan ṣe fun 'ra wa: ọkan ninu ohun ti a nsin awọn Oyinbo jẹ niyatọ lati ọpọlọpọ ọdun sẹhin wa, titi fi di oni, ni Ijo wọn ti a npe ni *Ball*: ti a ba bẹ itumọ Ijo yi wo, ọkan ninu ohun pataki ti awọn Oyinbo fi da silẹ fun ni ilu wọn, ni pe lati ma fi gi-ọn otutu nu, ni akoko rẹ: lọna bayi o jẹ iṣẹdalẹ wọn pe ki ọkunrin ati obinrin ma di mọ ara wọn ni Ile-Ijo (*Ball-Room.*) A ko si le ba wọn wi si eyi, nitori aṣa ilu wọn ni; "Ida'lu ni ṣe 'lu." Ṣugbọn nigbati awa Enia Dudu apa ibi gba aṣa yi nkọ, bi ẹni gba igba-ọti, oniruru iwa-ibi kọ lo bi sarin wa? Ẹ jẹ ki a wo ọrọ yi ni oriṣi ọna mẹta na. Ekini. Melomelo ni awọn ọdọmọkunrin wa ti nwọn ti nfi owo-iṣẹ Oṣu wọn tafala fun ipalẹmọ Ijo-Oyibiri-lagogo yi, nigbakugba ti a ba tẹ iwe sode pe Ijo na ya, nibiti gbogbo wa mọ pe nwọn ma njo o Ile Irati Afari Ogun (*Glover Memorial Hall,*) o ṣoro ki a to ri ọdọmọkunrin miran pe ki o lọ si Ipade Ọrọ-Asọye ti a tilẹ nṣe lọfẹ (*A free Lecture,*) fun rere ara rẹ: ṣugbọn e jẹ ki a to *Ticket* Ijo *Ball* kan ni Ṣile mẹwa-abọ tabi ni pọun kan ṣile kan, ọgafa iwọ yio ri ogun lọgọ ọdọmọkunrin ti nwọn yio si gan-ngan lọ sibi Ijo na. A tanma pe ko si ohun meji to ngbe nwọn lọ sibẹ ju ati ri aye lati ba pupọ awọn ọdọ-ọbinrin ti nwọn ko mọ ri jo, ati pe lọna bayi, lati wa aye ati ba pupọ ninu irufẹ awọn ọmọdan bẹ lorijẹ.

A ko sọpe ohun pataki ti awọn oninkan yi (Awọn Oyinbo:) fi da Ijo na si 'lẹ ni eyi; ṣugbọn iwa aitọ ti pupọ ọkunrin miran nhu si awọn obinrin lọna bayi nigbẹhin-gbẹhin ki i ṣe diẹ.

Ekeji. Iwa ọyaju ati irifin ti Ijo na nmu wa 'ko kere: ti ọdọmọkunrin kan ba ṣeṣi ri aya Alagba kan bajo ni ile Ijo (*Ball Room*) erokero kolẹ 'ṣai gba ọkan irufẹ ọdọmọkunrin bẹ kan lati wa ọna pe ki irufẹ aya-alaya bẹ le wa ni arọwọto on nijọmiran nigbati Ijo *Ball* ba tun kan: Ẹ jẹ ki a fi ero lu ohun ti o le ti idi irufẹ iwa wamọtipẹ bayi jade.

Ẹkẹta.* Ijo na si nkọ awọn ọmọbinrin wa ni iwa aṣa ti yio ma ye olukuluku wa: nitọripe kosi ọdọmọbinrin ti yio "saba" ati ma lọ si *Ball* ti ko ni fi "gọgọ fa" ohun ti ọwọ rẹ ko ti to: ti ko ba ni ipa ati ra nkan na, ko ha di pe ko wa "wọrọkọ fi ṣ' ada" ati wa ọna ati tọrọ owo lọdọ ọ unrin? Iredi rẹ nkọ? Ki o ma ye ọ! Nitotọ, alawọṣe ni a jẹ ninu aṣa Oyinbo yi, tiwa si "buaya" bi ẹnipe awa papa ko ni Ijo tiwa gẹgẹbi Orilẹ-ede ti a le tunṣe fun idaraya wa; o tilẹ d' ẹni, o d' eji, o di ẹmẹlo ni a nri awọn Oyinbo ti nwọn njo Ijo Ilẹ wa pāpā; awọn bi ijo Batakoto, Ṣẹkẹrẹ, Dudun at oniruru Ilu bawọnni? Anu ṣe ni pe pupọ ninu wa jẹ "Adagba-mada-'nu": a kọ gbọdọ ni ero ati gbe ohun ti Ilẹ-wa niyi, diẹ, afibi a wo-nkoko ti āṣa-ālaṣa-laiṣe ọlọpa Ido ti o nmu awọn oni "*Bicycle*" nimukumu a sọ ara wa di "Ojo-wo-nkoko"!!! ni irufẹ ọna bayi, lọjụ wa, Ijo *Ball* ti di Ijo-kijo: a kosi ni ma a ni ọwọ ninu gbigbe-la-nkẹ rẹ mọ lati oni lọ. Ẹ jẹ ki a mọ pe o to asiko ati ma tun nkan wa ṣe ki a si ma a gbe niyi: Aiye ijọun ko jọ tiṣeyi.

"ORUKO ERU KO BA WA MU." Awọn oni lakaye ni a mbawi.

### IGBẸ L' OWO WA.

EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-owo wọnyi ti gba Oja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Idapọ-Owo (A. & E. T. A.)
£10 10 de £10 15 fun *ton* kan
Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co,) bakanna
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores) do
Miller do

EPO.

£21 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a daruko wọnyi gba *ton* kan.

COCOA

Lati £25 de £27 fun *ton* kan bakanna.

## AWỌN ỌMỌWE ILẸ WA.

Gbogbo enia lo nkigbe awọn ọmọwe wa nilẹ yi fun pe ọpọlọpọ wọn ni iwa wọn ko dara, ti wọn ko si nbikita ati ti ọmọ ẹnikeji wọn sinu koto lati gbe ara wọn ga. Ninu iṣẹ buruku yi, ko si ohun ti o jẹ pe wọn ko le lo lati fi ri pe iwa ika yi ṣe. Ni ilu Aganyi a ri bi o ti jẹpe awọn onibajẹ wa nibẹ, awọn ti o jẹ pe gbogbo Ọba ilu ni lati le kuro ninu Ajọ ilu wọn, ohun ti o ṣe ni lanu ninu rẹ ni pe Onigbagbọ ni wọn, ko si Imale ninu wọn, bẹni ko si si abọriṣa pẹlu. Bẹ si ni ni ilu wa yi pẹlu, ninu ohun gbogbo ti o buruju, awọn Onigbagbọ yi kọ ni o ha nje aṣiwaju, awọn ti o jẹ pe gẹgẹ bi ilaju wọn ati ẹkọ wọn; o yẹ ki nwọn ki oima fi aperẹ olukọ wọn han ni ọna gbogbo; ko ha to akoko fun wa lati bẹrẹ si inu ro pe kini ṣe ti o ri bayi, iha ṣe iwe ti a mọ, tabi isin ti a gba lo nmu iwa wa ri bayi, tabi ilaju ti a gba pẹlu rẹ ni.

Nigbati a ba ṣakiyesi pe awọn Onigbagbọ lo pọju ninu awọn ọmọwe wa, ti nwọn mọ ede ati aṣa Oyinbo daradara ju awọn isin ti o ku lọ anu ko le ṣe ki o ma ṣe ni lati ri pe ami Olukọ wọn ko nsi ninu iwa wọn, eyiti a sọ pe o ngbe orilẹ-ede soke.

Ẹ jẹ ki a wo awọn Iwe-irohin wa ni ilẹ yi, nitoripe iyẹn dabi Awo-jiji ti o nfi iwa ati ẹkọ awọn ti o nṣe han; awọn ti o nka wọn yio ma ṣakiyesi pe ninu ikan tabi meji, ohun ti a nri ka ninu rẹ ko jọ eyiti o yẹ ẹniti o la'ju ti o si jẹ ọmọwe ati Onigbagbọ lati ma kọ ọrọ aini ibọwọ fun Ọba ilu wọn, ede aḍakandeke, ati ki a si ma bu ẹniti o ba di wọn lọwọ ti ko ba jẹ ki ero inu wọn ṣẹ; ki a fi ọrọ Eleko ṣaperẹ, tani ko mọ pe ohun ti Eleko ṣe, ka tilẹ sọ pe o ṣe Ijọba, ko to nkan ti o le mu gbogbo ro-gbo-di-yan wọnyi wa, awọn tani ha wa ni idi rukerudo yi, bikoṣe awọn ọmọwe ti o jẹ Onigbagbọ; ninu iwe-irohin "*West Africa*" ni a ṣẹṣẹ wa ri idi ija yi pe ede aiyede ti o wa ki ṣe larin Ijọba ati Eleko, ṣugbọn larin Eleko ati awọn Dr. RANDLE ni, bi a ba si ro daradara, a o ri gbangba pe Ọgbẹni Oniṣegun yi pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ lo ti ngbidanwo pupọ pe ki ọrọ yi ma loju; a ko mọ ewo lo kan wọn ninu ọrọ yi, a ko mọ bawo ni ọrọ ilu onilu ṣe ya l'apọ wọn, ọsọṣẹ ni iwe irohin wọn fi nsọrọ alufaṣa si Ọba ilu, bẹni ọrọ Ọlọrun sọ pe "ki a ma bọwọ fun Ọba ati Ijoye rẹ," ọkan ninu awọn oniwe irohin ti o nṣe ohun alebu yi si Ọba wa, sọ ninu iwe irohin rẹ kan, nigbati o nda ọmọluwabi kan lohun, ẹniti o fi ọrọ Ọlọrun kọ Gomina wa lọrun nipa ọrọ ti Eleko yi, o ni "a ko nfi ọrọ Ọlọrun ṣe ilu" bi eyi ba jẹ otitọ ilu Gẹsi ko ni ri bi o ti ri loni yi, Ijọba Gẹsi eyiti o jẹ alabo wa ni ilẹ yi lori ọrọ Ọlọrun ni Ijọba wọn duro le, Onigbagbọ enia dudu ti apa ihin ni ọrọ Ọlọrun ko han ninu iwa wọn.

Nigbati awọn agbalagba kan, awọn ti o "n'ifọn, ti o sin l'ekanna" ngbidanwo ati sa'pa wọn pe ọrọ Eleko yi ko to ohun ti a le fun 'ka mọ lati ṣe ohunkohun, ti nwọn si pe gbogbo ara ilu lati fi ọwọ si iwe yi lati tun ọrọ yi la fun Gomina, ko si ohun ti awọn iwe irohin yi ko sọ tan, nigbati nwọn ri pe awọn ara ilu ko bikita ati gbọ tiwọn, nwọn wa bẹrẹ si awọn agbagba yi bi nikan o jọkan, nwọn ni nitori ati ri owo gba jẹun ni nwọn ṣe sọ pe awọn ma kọ iwe si Ijọba nipaṣẹ Eleko, Gomina ko ni gba, ati iru nkan bawọnni, ohun kan ni a fẹ ki awọn ti o nkọ iwe irohin yi mọ, on ni pe, iwe ti gbogbo wa nfi ọwọ si yi, a o fi ṣọwọ si Gomina lati mọ pe ọpọlọpọ wa lo fẹ Eleko yi a ko si le rọ ọ loye yi tabi ka ni ki o lọ sun gẹgẹ bi awọn oniwe irohin yi ti nfẹ.

Lati igbati a ti nka iwe irohin ti ilu Oyinbo irufẹ ki a ma sọ isọkusọ si enia tabi ki a ma bu enia ṣọwọn pupọ, a fi eyiti iwe irohin di nkan miran lọdọ enia dudu ti Eko nihin, irufẹ ọrọ ti awọn iwe irohin wọnyi nsọ si ADAMU fihan pe ẹkọ wọn ko ṣe wọn lore rara, bi ko ba ṣe bẹ, kini kan wọn pẹlu ADAMU; bawo ni ija isin onisin ṣe di tiwọn, a ni ireti pe nitori ati tubọ ni ilaju si i, ati lati mọ bi a ti ṣe sọrọ pẹlu ede ọmọluwabi ni a ṣe nran ọmọ lọ si ile iwe; a le bere pe kini ADAMU ṣe ti awọn ọmọwe Onigbagbọ yi fi nwa iṣubu rẹ, ADAMU yi jẹ pataki ninu awọn Ijọ Musulumi ti o wa lẹhin Lemọmu BURAIMỌ, nigbati ija wa

larin wọn, o wa ninu awọn ti o ba Lemọmu ṣe awọ, o mọ kewu pupọ, o si ri oye iwe diẹ; pẹlu diẹ na, o mu ṣanṣan akere-koro ni, enia kekere ko ṣe gbe, awọn Janma fi J' oye Akọwe, on si ni nwọn si fi iṣẹ ran lati ma fihan nigba gbogbo ija isin wọn ni nwọn nja, ati pe ko si ọrọ ti ilu ninu rẹ, o jẹ alore fun awọn enia rẹ ti o fi jẹ oye, o si nlo iba ipa ati oye rẹ lati ri pe ọrọ nwọn yọri si dãdã. O ṣe iṣẹ rẹ dãdã tobẹ ti gbogbo koto ti awọn ọta nwa fun wọn, awọn janma ko ko sinu rẹ; eyi dun awọn ọmọwe Onigbagbọ yi pupọ debi gongo, pe ADAMU kẹ! iwe wo lo mọ, awọn ndi nkan, o si ntu u, njẹ o di karewa, nwọn mu u lọ si Ajọ Igbimọ ti Aṣofin Ijọba, Olori Ajọ ni on ko ri si i, o ni ki nwọn wa omiran sọ, ko si ọna ti nwọn ko yba tan lati ri pe ifẹ wọn ṣẹ, ko si ebu ti nwọn ko fi bu u tan, nwọn gbagbe ọrọ orin Akewi funfun kan ti o ni :—

Ọla ati itiju, ko ti ipo kan dide,
Ṣe iṣẹ rẹ daradara, nibẹ ni gbogbo ọla wa.

Nitotọ ADAMU ANIMAṢAUN kò gun, bẹni ko sanra, ṣugbọn ẹda ti Ọlọrun rẹ fi da ni yi, bi o si ti wu Ọba Ad' Ẹda lo np' ebu rẹ. Mose, Anabi Ọlọrun, akololo ni, ṣugbọn "Oriṣa ri 'yun nilẹ, ko to yan ṣẹṣẹ ẹfun l'ayo," Ọlọrun lo nlo ADAMU fun awọn enia rẹ lati ko wọn jọ kuro ninu ikẹkun awọn pẹiyẹ-pẹiyẹ.

Awọn ti Ọlọrun fun l' aye ati ma wa ire awọn ara ilu wọn laika ohun ti awọn ọmọwe wọnyi nsọ si wọn lara si, ọ yẹ ki a ma gbadura fun wọn, ki a ma ranti pe, ko si ohun ti iru awọn ọmọwe wọnyi ko le da si arin enia ti o rẹ meji, ko si arosọ ati ahesọ ti nwọn ko le ju silẹ, ko si si ọgbọn ẹro ti nwọn ko le lo lati fi da inu aikonu silẹ; o yẹ ki a ma feti si isọkusọ wọn, ṣugbọn ki a kọ oju wa si ọna kanna ti a ti nba bọ, ki a si ma sa gbogbo ipa wa ni ọna ti o dara lati ri pe ohun ti a nfẹ tẹ wa lọwọ.

FANOKUN.

## Scripture Column.

### "ALL THAT GOD DOES, IS DONE WELL."

(BY M. BANKOLE FADIPE.)

Rabbi Akiba was once travelling through the country, and he had with him an ass, a rooster, and a lamp.

At night fall, he reached a village where he sought shelter for the night without success.

"All that God does, is done well," said the Rabbi, and proceeding towards the forest, he resolved to pass the night there. He lit his lamp, but the wind extinguished it. "All that God does, is done well," he said. The ass and the rooster were devoured by wild beasts; yet still he said no more than "All that God does is well done."

Next day, he learned that a troop of the enemy's soldiers had passed through the forest that night. If the ass had brayed, if the rooster had crowed, or if the soldiers had seen the light, he would surely have met with death, therefore he said again, "All that God does, is done well."

*The Talmud Page 266.*

The fool hath said in his heart, there is no God. *Psalm xiv. 1.*

Is anything too hard for the Lord?

*Gen. xviii. 14.*

"Thy yesterday is thy past; thy to-day thy future; thy to-morrow is a secret."

## SI AṢABOJUTO "EKO AKETE"

### LATI ỌWỌ ALAFIA.

Inu mi dun lopọlọpọ nigbati mo ri iwe "Eko Akete" ekini ti jade. Ṣugbon gẹgẹ bi o ti dun mọ ni ninu, bẹni o'ba mi lẹru to, nitori nigbati mo wo gbogbo ayan, lala, ati iyọnu ti o ti ṣe ni iru ọna bayi ni igba ti o ti kọja, mo ri wipe gbogbo rẹ fẹrẹ ku si asan, nitori o dabi aṣedanu. Ṣugbon Ọlọrun ko ni jẹ ko ṣe iṣẹ aṣedanu!

Awa ara Eko ko ni asapẹ arara, a ko si ṣe gbọkanle. Bi a ba ru si oke fun sa diẹ, ni aipẹ ao tun rẹlẹ gẹgẹ bi igbi omi okun. Eniti o ba fẹ ma ṣe iwe irohin fun ilu rẹ yio joye "Ojo ko ba enikan ṣọrẹ," yio jẹ oloto enia; nitorina mẹlọmẹlọ dọwọ rẹ. Ti o ba fẹ ki iwe rẹ ṣe ilu yi ni ore, o ni lati duro ti otitọ, lọsan loru ati ni abusudaju. Ma jẹ ki owo mu ọ purọ, ma jẹ ki o mu ọ sọ asọdun. Bi ọrọ ba ti ri gan, bẹni ki o ma sọ. Ki Ọlọrun ki o ran ẹ lọwọ lati ṣe rere fun ilu wa yi gẹgẹ bi o ti ngbidanwo lati ṣe lati iṣiwaju.

Ngo ma gbidanwo lati ran ọrọ diẹdiẹ si ọ nipa oniruru nkan ti mo ro pe o nfẹ ibẹwo larin wa, mo si tanma pe ọrọ mi ki yio mulẹ mofo.

*Nję mo bęrę*

## ILU EKO.

Eko Akete ile ogun. O ma şe o! Nję ara ilu miran kọ ni o nfi ọgbọn ti o wa l' Eko şere nibayi, o pa şe awa papa ni ire bi? A ri wipe bi o ti jępe ogbon wa li Eko to, o da bi ęmpe awa ara Eko ti ri ọgbọn na fin tobę o ti a ko le lo fun ire ara wa. Nitotọ ni nwọn ma wipe "Ogun ti a ko ba fi owo ra, ęhin aro ni igbe." Nigbati aba bę ilu wa yi wo, nję ọkan wa ki ręwęsi. Eşe ti ede-koyede şe pọ tobę larin wa? Ọran wa na ti kọja ọrọ şereşere, o ma ti kọja oro yęyę. Ọlọrun da wa si aiye lati ma jumọ damọran, şugbọn nibiti mo-mọtan enia ba wa, ti eke ati agabagebe ba wa, ti onigberaga ati onigbera-şọnlę ba wa, ti wọbia ba wa, ati ti alaişotọ ati onibitibiti ba wa. nibiti ikorira ara ęni ba wa, nję eyi ha le şe şe? A ha le damọran ohun kan. Ę ję ki a yę ara wa wo. Ęnyin agbagba ti o nba ọmọde wi pe ija ko dara nje ęnyin papa ko ti di atępọ-ija-ję bayi? Arun ti o mu iwọnyi wa ni mo ti sọ siwaju. Kini le wo arun wọnyi san. Ifę ilu wa, Nigbati a ba tan siwaju, ti a ba tan sęhin, nko ro pe a le ri ęnikęni ti o le fọwọ sọ aiya pe on fęran ilu yi nitotọ. Bi iru rę bawa, ki o dide ki o tun ilu wa şe. Ni akoko ti awọn Captain DAVIES, Ọgbęni LEIGH, Ọlọla GEORGE (ỌŞỌBA.) BUCKNOR ati awọn miran nşe ilu, ko ma dorikodo bayi, nitorina, ę ję ki a bę ara wa wo. Yamọti ti da mọ 'yępę Ọlọrun nikan lo ma le yan o! Ęsọ ma di ọwọ wa. O dami loju pe, ti a ko ba fi keta ati irira şe ohunkohun ti a ba dawọle, yio yanju si rere Kini iwe Bibeli wi; "ohun ti a ba gbin ni a o ka." Ęję ka gbin ohun rere silę fun awọn ọmọ wa!

## AJỌ-IGBIMỌ ILU TITUN TI A FĘ DA SILĘ NI NIGERIA.

Eyi yio ję ayipada, tabi ohun titun larin wa, ti a si ro pe yio mu ire wa ba ilu wa dandan. Şugbọn ewu nla ni nbę ninu rę fun awa ara Eko. Awọn ęlomiran ro pe a ko iti dagba to lati ni iru igbimọ bayi, nitori oju ko iti la to, şugbọn awọn miran ro pe o to akoko ti o yę ka fun Eko ni iru anfani ti a fę lati fun. Ti ọmọde ba to ni apo ani apo. O di ọgọta ọdun ti Ijọba Gęsi ti gba itọju ilę yi sọwọ wọn. Ọpọlọpọ ohun ni wọn si ti şe fun ilọsiwa ilu yi, bęni ọgọrọ nkan ni nwọn ti şe ti ko dunmọ awa ara Eko ninu. O le ję pe wọn nşe ohun miran ti wọn ro pe yio şe wa ni ire nigbamiran ti a ko mọ, ti a si ma npe ni ibi, şugbọn a ko le fę iru ohun bayi ku Ajọ-Igbimọ titun yi şa yio ję fun ilọsiwaju ilu wa. Şugbọn ki ma şe ohun ti awa ara Eko yio fi jęlęnkę şe o. Nko ję ba awọn ti o sọ wipe a ko iti to ni iru anfani bę wi pupọju. Ęru ni nba wọn! Arọba si ko ma şojo. Sibę, "ijọ kan ni igi m' oju ina." A ha le ma fa ni ni tętę titi aiye. Ęję ki awa na gbidanwo lati fun rawa. Ọgọta ọdun ha nşe ọmọde ọdun bi? Ohun kan şa ni on ba ni lęru giğigidi: A sọ fun ni pe awa ara ilu yi yio ni lati yan awọn enia męta ni Eko sinu Igbimọ yi. Ti a ba fi oju-saju yan awọn męta wọnyi, ara wa la ma nşe o. A ni lati yan awọn ti yio to lati gba ọran wa dun ni Igbimọ na ni, awọn ti yio sọ otitọ fun wa, ki şe awọn ti o fę iyi nitori iyi lasan, ki şe işę awọn ti o nsọrọ alupa-yida şugbọn awọn ti o fęran ilu wọn fuu rere. Wọn şoro lati mọ o. Ninu rogbodiyan ilu wa yi, iru awọn enia ti o yę lati yan si Igbimọ wa lọtun wọn si wa losi, nitorina nigbati o ba ya, a ni lati woye daradara ki a to yan wọn. Ilu ti o ba da si ọna meji ko male duro! Ilu Eko kole toro ti a ko ba dawọpọ ti a ko ba si damọpọ. Eyiti a gbogun ti ara wa yi, o ha tọ? Ę ję ki a bę ara wa wo! Ija ko şe ilu kan ni ire ri, ko si 'e şe ara Eko ni ni ire. Ęnyin agbagba ilu, ọwọ 'yin lowa o! O dọwọ nyin o!

## ORIN ILU WA NI ILE-ĘSIN

O ję ohun ti o dun mo ni lọpọlọpọ lati ri pe awọn Ijọ ti o wa ni abę itọju awa ęnta dudu nşe orin ilu wa ti a nkọ ni ile-ęsin. Eyi ję ohun ti o dara lọpọlọpọ, o si fun ni işiri. Nitori nigbati a ba ni ohun bę, o fi hanni gbangba pe gęgę bi orile-ede, awa na ni ohun tiwa, a si ni Iakaye. O ję aşa wa, pataki larin awọn aşęşę dide wa, lati ma şata ohunkohun ti o ba ti ję ti ilu wa. Şugbọn iwere nla ni eyi.

Ę ję ki a mu ohun ti o dara ni tilu wa dani giri-giri, ki a kọ ohun ti ko dara ninu rę silę patapata. A kiyesi pe bi awọn ti o nşe orin wọnyi ti ngbidanwo to yi, o ku dię ko to. Nigbati a ba fę şe iru orin ęsan .bawọnyi o yę ki a ma ro jinlę daradara. A ni lati mu ohun iręlę ati ębę kọ orin ti ọrọ rę ję ti ębę ati iręlę, eyiti o ba si ję ọrọ ayọ, o yę ki a ma fi ohun ayọ kọ, nigbati a ba mu ohun ayọ ti a ba fi nkọ ọrọ ędun, yio di amulu-mala. Eyi ko dara. Nisisiyi, a ri pe ohun ti o ba wun wa şa ni a fi nkọ ọ, ti o ba sa ti ndun yungba a ko bere. Ę ję ki a ma şakiyesi ohun wọnyi, "Ika ti o ba wọ imu la ki bọ ọ." Mo ro pe awọn ti o nşe orin iruwọnyi yi o ma şe akiyesi ohun bayi ti wọn ba fę şe orin. Nigbana ni ao le gbadun işę ọwọ wọn.

## MAMMY RE 'LE O, ILE LO LỌ KO ŞINA.

A ba Alufa J. M. Ologundudu ti Ilu *Sapeli*, ati Mrs. O. A. Rieff ti No 2 Ita Rieff, l' Eko daro ọfọ to şe wọn ni *Monday* ọsę yi nipasę iku iya wọn SARAH FATOKUN.

K' Oluwa dę 'lę fun u.

## ARNOLD SCHLESINGER.

OYINBO JAMANI ONIṢOWO ARA HAMBURG

Ṣi Ile-Owo rẹ si *No.* 7, Ità Labinjọ, l' Eko.

Ọgbẹni Oyinbo Jamani yi ti ṣe "kokari" ati fi awọn ogunlọgọ Irepe-Aṣọ tita rẹ han enia, ni Ile-Owo rẹ ni *No.* 7, Ita Labinjọ, ko jinna si Ita Williams, l' Eko: o si tun ni Ile-Owo ni Ita Akwaesuk, ni Ilu Calabar.

A pe gbogbo enia ti o ba fẹ ba wa ra ọja, lati wa wo oniruru Ọja wa, ati awọn Irepe-Irepe Aṣọ l'oriṣiriṣi, tabi Iwe-Aworan Ọja wa. A ti nṣowo lati igba "na-mi nna'lẹ" eyini ni l'ojọ pipẹ lati ọdun *1842*: ina owo wa si ti njo geregere ni Apa-ibi ti o jẹ Ilu Enia Dudu lati iwon ogun ọdun sẹhin titi di oni. A si ni "wabi-wosi" awọn onibara ti Ọja wa ti dun mo. Awa nikan l' o nta awọn MASINI IRANSO ti a npe ni "ADLER" ati eyiti a npe ni MUNDLOS (eyi ti a npe ni VICTORIA ri). A si ni MASINI ti awọn Aranbata, ti Aranṣọ ati fun lilo ni 'le. A nta kẹkẹ pupupu (*Motor Bicycle*) ti a npe WANDERER pẹlu ẹrọ-ere sisa rẹ, ati eyiti a npe ni "GOLD COASTER" a si ni *Bicycle* lasan ti a npe ni "COASTER." A ni awọn Egbogi t' o jẹ bi Idan ti a npe ni BULA MATADI ati MOLOKE MONE. A si ni awọn Aworan: oniruru aworan bi ti Oluwa nigbati o wa ni Mọṣalaṣi ni Ilu Oyinbo. A si ni Duru ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ ti o mọ niba fun gbigbe kiri, a si ni Ẹrọ-Olorin (*Gramophone*). A si ni *Cement*, Panu Kikọle, Jigi ti Ferese ati pupọ nkan miran.

A le gba Ekurọ, *Cocoa*, tabi Epo dipo Owo-Ọja ti ẹnikẹni ba ranṣẹ lọdọ wa.

Ẹ wawo, Ọja wa pọ to gbajẹ.


## Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O!

OWO IRANLOWO TI A ṢI RI GBA NI WỌNYI.

| | £ | s. | d. |
|---|---|---|---|
| Owo ti a ti ri gba | 7 | 16 | 0 |
| Ọgbẹni Saka Tinubu | 0 | 10 | 0 |
| " Oke Adeṣigbin ... | 0 | 5 | 0 |
| " Yesufu D. Martins | 0 | 5 | 0 |
| " Saka Dabiri | 0 | 3 | 0 |
| " Alfred Falade | 0 | 2 | 6 |
| Aropọ | £9 | 1 | 6 |

**Ara ilu, Ẹ jare Ẹ ma jẹ ko rẹ nyin, A o ma jihin yi lọsọsẹ,**

**[ED.—E. A.]**

## PREACHERS FOR TO-MORROW.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

| (Morning.) | Masses Isin Aro, |
|---|---|
| 6.30—7.30 | 8.30—8.30 |
| 7.30—8.30 | 93.0—10.30. |

(Evening.) Masses (Benediction) Isin Ibukun
4.45—5.30 6.45—7.30.

**ANGLICAN**

Time. Preacher.
9 a.m.—Christ Church Rev: H. Dallimore
6.30 p.m. Rt. Rev. Bishop of Lagos
9 a.m. & 6.30 p.m.—St. Paul's (Breadfruit) Ven Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
9. a.m.—St. John's (Arọlọya) Rev. H. V. E. Johnson
9 a.m. 4 p.m.—St. Peter's (Alapako) Rev. J. A Cole
9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) Rev. S. J. Gansallo.
9 a.m.—St. David's (Jordan Rev. J. A. Leigh

**WESLEYAN**

10.30 a.m.—Tinubu Rev. E. K. Ajai-Ajagbe
7 p.m. Rev J. C. Cole
10.30 a.m.—Ereko Rev. A. N. Cole
7 p.m. Bro. S. O. Stowe
10.30 a.m.—Olowogbowo Rev. E. E. Williams
7 p.m. Rev. D. A. Beckley
10.30 a.m.—Ọbun Eko Rev. D. A. Beckly
7 p.m. " E. E. Williams

**AFRICAN (COMMUNION)**

9 a.m.—Jehovah Shalom Rev. Supt. G. A. Oke
7 p.m. Rev. J. F. Ogunko
9 a.m.—Erelu Bro. A. M. Williams
4 p.m. Bro. J. H. Lawson
9 a.m.—Bethel Rev. H. Atundaolu
4 p.m. Bro. A. Aboyade Cole
6.30 p.m. Bro. J. B. Coker
10.30 a.m.—African Methodist Bro. H. A W'ms
4.30 p.m. Bro. F. M. Wilson
9 a.m.—Araromi Church Bro. E. A. Ojo
4 p.m. Bro. S. M. Phillips

**EBENEZER**

9 a.m. Rev. A. A. Puddicombe
6.30 p.m. Bro. Joseph Adekoya

**St. STEPHEN'S (EPETEDO.)**

9. a.m. Very Rev. J. G. Campbell
4 p.m. Rev. J. Adekoya

**BROTHERHOOD.**

7.30 a.m.—Ilupesi Bro. Fagbemi Faṣeyi
7 p.m. " Pastor A. Adeleji Iṣọla

**AHMADIA.**

5.30 p.m.—Open Air Service Prof. A. R. Nayyar (Vincent Street.)

**COLONIAL CHURCH. (ODAN)**

A nyan Awọn Alufa si Ile Isin yi lọsọsẹ.

## THE "AJENIFUJA" SEWING MACHINES.

These Machines are German Manufactured. Constructed of the best materials and skilful workmanship, very splendid in appearance, quick action and noiseless. No confusion, simple to thread, easy to operate. Durability Guaranteed will last almost life time, call for one at ORI-ADE STORE 97 & 109, Broad Street Lagos. Needles, Shuttles, etc., etc. in stock. Prices on application.

VIDAL R. COLE,
*Sole Agent.*

## "OṢEWỌNI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko. O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

### N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.
## J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street,*) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi uranşẹ MAŞINI-ARANŞO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati şe Adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mẹjila tabi ju bẹ lọ ninu MAŞINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, Nwọn si nranşẹ (*Cemet*) ati panu kikọle to nipọn, ati Ẹja Abọmafọ ati Orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AŞIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Ọ. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aşẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ILE OWO-ỌJA RIRANŞẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Şẹda, Onini, Owu-Şẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ (*Felt*) Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kọtu, l' Eko.

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.
### ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo Abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

## ILE EGBOGI IŞẸ OLODUMARE.

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Işẹ Olodumare si Ọja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaşe fun Orififo, Inurirun, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọşẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.
Iwọ ko tile gbọ oruko rẹ ndan?
Işẹ Olodumare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## Advertisements.

IPOLOWO ỌJA.

—:o:—

### ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣowọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ

108, Moloney Bridge St.

P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.

——o——

READY.

"Church and Politics."

(A Lecture)

OR

The Duty of the Clergy to the Laity.

By Prof: DENIGA.

SOLD at 24 Williams Street, Lagos.

3d. a copy.

AWON ẸGBE OYINBO ONIṢOWO TI A NPE SI

E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ Enia Dudu, nwọn ni nranṣẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ'ibaṣe Ọja ti Ilu Ge[...] tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ta o wa lagbegbe *England* ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti [...] ba fi ranṣẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Kosi ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranṣẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo jọ[...] tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Karim Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No 3. tabi ni ibi-iṣẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L[...] Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg

GID'GBO! GID'GBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.

8, Tinubu Square, Lagos.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?

Ki la ti nṣ' ori nile Iku?

Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni

8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


Printed at "Tika-Tore" Printing Works, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer